# IJỌBA ẸGBẸRUN ỌDUN ATI IDAJỌ IKẸYIN
## Ifihan 20:1-15
### ẸKỌ 465-- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Bi a ba si ri ẹnikẹni ti a kò kọ orukọ rẹ̀ sinu iwe ìye, a sọ ọ sinu adagun iná" (Ifihan 20:15).**

**Angẹli ti o ni Ẹwọn**

Ninu ori iwe yii, a kà siwaju si i nipa awọn ohun nla ati ohun iyanu ti Johannu rí. Angẹli kan sọkalẹ lati Ọrun wá, ti o ni iṣika ọ̀gbun nì, ati ẹwọn nla kan ni ọwọ rẹ̀. O fi ẹwọn naa de Eṣu o si gbé e sọ sinu ọgbun ainisalẹ, o si ti i mọ́ ibẹ, o si fi èdidi di i lori, ki o má ba le yọ bọ́ fun ẹgbẹrun (1,000) ọdun.

Ninu awọn ẹkọ wa ti a ti ṣe sẹyin, a ti kọ́ ẹkọ pe Eṣu ti bẹ̀rẹ si i tan eniyan jẹ lati ibẹrẹ ayé. O mú ki Adamu ati Efa jẹ ninu eso ti o wà ninu Ọgba Edẹni eyi ti Ọlọrun ti sọ pe wọn kò gbọdọ jẹ. Nitori aigbọran yii ni ẹ̀ṣẹ, aisan, wahala ati ikú fi wà lori gbogbo ayé fun nnkan bi ẹgbaata (6,000) ọdun.

**Eṣu--"ejò atijọ nì"**

Eṣu ni o maa n dán eniyan wò lati ṣe buburu; oun ni o maa n mu wọn ṣiyemeji Ọlọrun, ati lati ṣe aigba Ọrọ Rẹ̀ gbọ́; oun ni o maa n ṣiṣẹ lori ẹni kọọkan ti o si n gbiyanju lati jẹ ki oluwarẹ̀ lọ si ọrun egbe nikẹyin. Olukuluku Onigbagbọ́ gbọdọ fi pẹlẹpẹlẹ pa ọkàn rẹ̀ mọ́, nitori ọta ẹmi n gbiyanju lati mu ki o sọ igbala rẹ̀ nù. Onitanjẹ ati eleke ni oun i ṣe. Ẹ ma ṣe jẹ ki a fetisi eke rẹ̀ rara. Agbara Ọlọrun pọ̀ o si lagbara ju ti Eṣu lọ, Oun si le pa wa mọ́ kuro ninu iṣubu, bi a ba fẹ ki O pa wa mọ́. "Ẹniti o ba ṣẹgun ni yio jogún nkan wọnyi" (Ifihan 21:7).

Lati igba ti Eṣu ti ni iṣẹgun lori Adamu ati Efa, ni o ti n ṣiṣẹ ti o si n gba aṣẹ lori igbesi-ayé ọpọlọpọ eniyan si i, nitori naa ni o ṣe jẹ pe ni akoko ikẹyin yii, n ṣe ni nnkan tubọ n buru siwaju ati siwaju. Awọn ijọba ayé ati awọn ilu n gbé Kristi tì si apa kan, wọn si n yipada si "ejò atijọ nì" ati agbara rẹ̀.

A kọ́ ninu ẹkọ wa ti o kọja pe Kristi ati awọn eniyan mimọ́ Ọlorun yoo pada wá si ayé, lori ẹṣin funfun lati wá ṣe akoso ati lati jọba lori ilẹ ayé fun ẹgbẹrun (1,000) ọdun. Eyi ni akoko ti o wà laaarin Ipọnju Nla ati idajọ ikẹyin niwaju Itẹ́ Nla Funfun. Eyi ni akoko ti a o fi ẹ̀wọn de dragoni naa, "ejò atijọ nì, ti iṣe Eṣu, ati Satani," ninu ọgbun ainisalẹ, alaafia yoo si wà lori ilẹ ayé fun ẹgbẹrun (1,000), ọdun.

**Ijọba Ẹgbẹrun Ọdun**

Eyi yoo jẹ́ akoko alaafia nigba ti Kristi yoo "mu ọ̀tẹ tan de opin aiye" (Orin Dafidi 46:9). Awọn eniyan ayé ti n jagun lati igba ti ayé ti bẹrẹ, ṣugbọn a sọ fun wa pe ni akoko Ijọba Ẹgbẹrun Ọdun "nwọn o fi idà wọn rọ ọbẹ-plau, nwọn o si fi ọ̀kọ wọn rọ dojé; orilẹ-ède ki yio gbe ida soke si orilẹ-ède; bẽni nwọn ki yio kọ́ ogun jijà mọ́" (Isaiah 2:4; Sekariah 9:10). Ni akoko naa, gbogbo eniyan ni yoo wá sabẹ ijọba Kristi, a o si dá wọn silẹ kuro ninu gbogbo arùn ati aisan. "Oju awọn afọju yio là, eti awọn aditi yio si ṣí. Nigbana li awon arọ yio fò bi agbọ̀nrin, ati ahọn odi yio kọrin" (Isaiah 35:5, 6).

Gbogbo nnkan ni yoo lẹwa ti yoo si dara ni akoko alaafia ati ayọ̀ yii. Awọn iṣàn omi ati itanna yoo wà ni ijù, awọn adagun omi yoo si wà dipo ilẹ gbigbẹ. Awọn ẹranko buburu paapaa yoo wà ni alaafia a o si tù wọ́n loju. Ejò, ikooko ati kiniun, maluu ati beari yoo maa jẹun pọ̀ lai si ipalara. A sọ fun wa pe kiniun ti n pa awọn ẹranko keekeekee yoo jẹ koriko bi maluu. Awọn ọmọ-ọwọ́ paapaa ati awọn ọmọde yoo wà lai lewu ati lai ni ipalara lati ọwọ́ awọn ẹranko buburu.

Awọn oyin ki yoo ta ni mọ́; awọn itanna ki yoo ni ẹ̀gun lati gún wa ni ọwọ́ mọ; awọn eso ajara ki yoo ya ni lapa bẹẹ ni ki yoo ya wa laṣọ mọ. Awọn afọju yoo le riran; awọn aditi yoo gbọran; awọn odi yoo si sọrọ pẹlu. Kò si ohun ti yoo panilara, tabi panirun "ni gbogbo oke mimọ́ mi, li OLUWA wi" (Isaiah 65:25). A kà pe ni Jerusalẹmu "igboro ilu yio si kún fun ọmọdekunrin, ati ọmọdebinrin, ti nṣire ni ita wọn" (Sekariah 8:5).

**Adagun Iná**

Nigba ti akoko naa ba pari, a o tú Satani silẹ kuro ninu tubu rẹ̀, ninu ọgbun ainisalẹ, yoo si tun gbiyanju lati ja ogun nla miiran. Ṣugbọn a o gbe e sọ sinu adagun iná ati sulfuri, nibi ti ẹranko ati wolii eke naa wà, wọn yoo si maa joró ni ọsan ati ni oru lae ati laelae. A mọ̀ pe ẹranko naa ki i ṣe ẹlomiran bi ko ṣe Aṣodisi-kristi. (Wo Ẹkọ 413).

**Itẹ́ Idajọ Nla Funfun**

Lẹyin eyi, Johannu ri Itẹ́ Funfun nla, o si ri awọn eniyan ti wọn ti kú n jade wá siwaju Ọlọrun, wọn si duro niwaju Itẹ́ lati gba idajọ. O si ri awọn iwe ti a ṣí, a si ṣi Iwe Iye pẹlu, a si dá awọn eniyan lẹjọ gẹgẹ bi awọn ohun wọnni ti wọn ti ṣe ti a ti kọ sinu awọn iwe wọnni. A ṣi isa-okú, awọn ti wọn ti kú sinu ẹ̀ṣẹ wọn paapaa ni ọpọlọpọ ọdun sẹyin, lati ipilẹṣẹ ayé, ati awọn ti wọn kú si okun paapaa tabi awọn ti a jó ti a si parun, ni a ji dide, wọn si duro niwaju Itẹ́ lati gbà idajọ. Gbogbo awọn wọnni ti a kò ri orukọ wọn ninu Iwe Iye ni a gbé sọ sinu adagun iná nibi ti a ti gbé Eṣu ati Aṣodisi-kristi sọ si tẹlẹ, ki a ba le maa dá wọn loro lọsan ati loru lae ati laelae.

**Orukọ Wa Ninu Iwe Iye**

Ohun pataki ti o yẹ fun wa lonii ni lati ri i daju pe a kọ orukọ wa sinu Iwe Iye. Bi a ko ba i ti gbà ọ̀ là, wá sọdọ Jesu lonii; beere lọwọ Rẹ̀ pe ki O dari awọn ẹ̀ṣẹ rẹ jì ọ; ṣe atunṣe awọn ohun ti ko dara ti o ti ṣe si awọn ẹlomiran. Nigba ti o ba ni idaniloju pe Jesu ti dariji ọ, gbadura sọdọ Rẹ̀ fun isọdimimọ́ ati agbara Ẹmi Mimọ́. Lẹyin naa tẹle Jesu timọtimọ; gbadura ki o si ka Ọrọ Ọlọrun; ri i daju pe a ko pa orukọ rẹ rẹ́ kuro ninu Iwe Iye.

**Iye tabi Ikú**

Ọna iye ainipẹkun ati ọna ijiya ati ikú ayeraye wa niwaju wa. Bibeli wà ni arọwọto wa lonii, ninu rẹ̀ ni a ti le kọ́ ọna ti a o fi maa gbé igbesi-ayé wa lojoojumọ ki a ba le wà ninu awọn wọnni ti a kọ orukọ wọn sinu Iwe Iye. Ṣe akiyesi pe ẹsẹ kejila ati ẹkẹtala sọ fun wa pe a dá awọn eniyan ti wọn wà niwaju Itẹ́ lẹjọ "gẹgẹ bi iṣẹ wọn." Ha, wo bi o ṣe yẹ lati gbé igbesi-ayé wa pẹlu iṣọra to! Bi o ṣe yẹ lati ṣọ́ igbesi-ayé wa ati awọn ọ̀rọ wa to, ki a má ba mu inu Oluwa bajẹ ninu ohunkohun. Kò ni si asala ni ọjọ naa nigba ti ewe ati agba, ọlọrọ ati talaka yoo duro niwaju Itẹ́ Funfun nla ati Ẹni ti o joko sori rẹ̀.

**AWỌN IBEERE**

1 Orukọ miiran wo ni a n pe Eṣu?
2 Bawo ni a ti de e sinu ọgbun ainisalẹ pẹ́ tó?
3 Ṣe alaye iru ipo ti ayé yoo wà nigba naa?
4 Ta ni yoo ṣe akoso ayé nigba Ijọba Ẹgbẹrun Ọdun?
5 Ta ni yoo fara hàn niwaju Ọlọrun nibi Itẹ́ Idajọ Funfun nla?
6 Lati inu ki ni a ti ṣe idajọ awọn eniyan?
7 Ki ni yoo jẹ́ iyà awọn wọnni ti a kò kọ orukọ wọn sinu Iwe Iye?
8 Ki ni ere ti a o fifun awọn wọnni ti a kọ orukọ wọn sinu Iwe Iye?